# AWORAN PẸLU IROHIN



## Gomina pade awọn ọba, onirohin

"ATILẸHIN pẹ̀u ifọwọsowọpọ awọn Ọba, Ijoye ati gbogbo enia kakiri ipinlẹ yi ni emi nfẹ." Alaye yi ni ara ọrọ ti Gomina Ologun Ipinlẹ yi, Ọgagun Oluwọle Rotimi mba awọn Ọba alade sọ nibi ipade ijiroro kan, eyiti o ba awọn ọba alade se ni ile iṣẹ rẹ ni Ibadan ni ọjọ Ọjọ'Ru ti o kọja yi. Dajudaju, aworan apa osi yi nfi apẹrẹ iru irẹpọ eyiti Ọgagun Rotimi nfẹ lati ọdọ awọn Ọba alade ipinlẹ yi han.

T'ẹrin-t'ẹrin ni Gomina na fi ngba awọn ọba alade l'alejo. O si ba wọn sọ oniruru ọrọ iwuri, eyiti o mu ki ayọ nla kun ọkan awọn ọba.

Wo aworan apa osi yi dara-dara, iwọ yio ri Alaiyeluwa Ọlọla Adesọji Aderemi Ọni Ife l'apa osi, nigbati o nfi awọn ọba alade ẹlẹgbẹ rẹ han Gomina. Alafin ilu Oyo Ọba Lamidi Olayiwola Adeyẹmi ni ẹ nwo ti o mbọ Ọgagun Rotimi lọwọ ninu aworan yi. Eniti o duro l'apa osi Ọba Adeyẹmi ni Ọba Agunlejika Owa ilẹ Ijẹṣa. Awọn Ọba alade yoku na fi t'ifẹ-t'ifẹ duro lati ki Ọgagun Rotimi.



Awọn onirohin oniṣẹṣẹ wura kakiri ipinlẹ yi ko ipa pataki ninu atunse ati igbega ipinlẹ yi. Apẹrẹ yi ni Ọgagun Rotimi nse afihan rẹ (wo aworan apa osi yi) nibi apejẹ nla kan, eyiti o pe fun awọn Ọga onirohin ni ile rẹ ni Iyaganku, Ibadan laipẹ yi. Aworan na nse afihan Ọgagun Oluwọle Rotimi (ẹniti ami itọkasi wa lori rẹ) nigbati o mba awọn Ọga onirohin sọrọ nibi apejẹ nla ti o pe wọn si na.

Aworan isalẹ yi nfi Iyafin Ayọ Ogun, Akọwe agba fun Ẹgbẹ Apapọ Obinrin orilẹ-ede yi han nigbati o mba apejọ ẹgbẹ obinrin ẹka Ipinlẹ Kwara sọrọ nibi ayẹyẹ ase idanilọla eyiti ọmọ ẹgbẹ na ṣe fun un ni ilu Ilorin laipẹ yi.

## O KU ORIRE

Idunnu ṣubu l'ayọ fun Ọgbẹni Balogun Quadri nigbati o jẹ ẹgbẹrun pọnun (£1,000) nibi idije orire Stoke City Fixed Odds ti ọsẹ ti o kọja yi. Dajudaju, ẹbun Alayo L'apo: eyiti iwe irohin "Gboungboun" ngbe jade l'ọsọsẹ ti se ọpọlọpọ enia ni anfani. Wo aworan isalẹ yi dara-dara, iwọ yio ri Ọgbẹni Quadri (L'apa osi) nigba'ti o ngba ẹbun ẹgbẹrun pọnun, owo orire na lọwọ Ọga ile iṣẹ orire (Stoke City). Ọgbẹni T. Olasanya. Eniti o duro l'apa otun ni Ọgbẹni J. Q. Odukọya, Oludari ile iṣẹ orire na. T'ẹrin-t'ẹrin ni Ọgbẹni Quadri fi ngba owo 'apekanuko' na lọwọ Ọgbẹni Olasanya.







OGBẸNI M. F. McEwen, Alaga Ẹgbẹ Olupolowo Ọja (Nigeria Advertising and Publicity) pe apejẹ nla fun igbadun ọga ile iṣẹ rẹ. Awo na apa ọtun yi nse afihan Ọgbẹni McEwen nigbati o mba awọn ọga ile iṣẹ rẹ sọrọ nibi apejẹ na. Lati apa ọtun: Ọgbẹni Leke Oyekan, Akọwe agba ni ile iṣẹ ipolowo ọja na; Ọgbẹni J. K. Arọloye, Igbakeji Alaga ile iṣẹ na; Ọgbẹni McEwen, Alaga; pẹlu Ọgbẹni Rẹmi Adeoye.

Aworan apa osi nse afihan Ọgbẹni J. O. Sanya, aṣoju fun ile ifaja pako (African Timber and Plywood) ni Ibadan nigbati o ngba iwe ẹri ipo kini lọwọ Ọgbẹni D. R. Salt, alaga Igbimọ Olufihan Ọja orilẹ-ede yi. Ile iṣẹ ifaja pako yi ni ibuso ọja rẹ dara julọ nibi afihan ọja orilẹ-ede yi, eyiti awọn ṣe ni ilu Ibadan laipẹ yi.



